# IRUGBIN MUSTARDI ATI IWUKARA

## Matteu 13:31-33

## ẸKỌ 77 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ki ijọba rẹ de; Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹ̃ni li aiye" (Matteu 6:10).**

**I Ibẹrẹ Ijọba Naa lati ibi Kekere**

1. A fi Ijọba Ọrun wé wóró irugbin mustardi, Matteu 13:31
2. Ọkunrin kan mu wóro irugbin mustardi naa, o si gbin in si oko rẹ̀, Matteu 13:31, 37, 38
3. Irugbin mustardi ni a woye pe o kere ju gbogbo irugbin yoku lọ, Matteu 13:32; 17:20

**II Titobi Ijọba Naa Nikẹyin**

4. Nigba ti o dagba tán, mustardi naa wá tobi ju gbogbo igi lọ, Matteu 13:32; Marku 4:32
5. Ni titobi ati irisi rẹ o fara jọ igi pupọ, Matteu 13:32;Esekiẹli 17:22-24
6. Awọn ẹka rẹ jẹ́ ibukun fun awọn ẹyẹ, Matteu 13:32;Gẹnẹsisi 12:3; Isaiah 2:2-4

**III Idagbasoke Ijọba ti a kò fi Oju Ri Naa**

7. Awọn otitọ nipa Ijọba Ọrun dabi owe iwukara, Matteu 13:33
8. Obinrin kan mu iwukara naa, o si fi i pamọ sinu oṣuwọn iyẹfun mẹta, Matteu 13:33; Luku 17:20, 21
9. Ohun ti iwukara naa wa fun ni pe ki o le wọ inu gbogbo iyẹfun naa, Matteu 13:33; 4:23; 24:14

## ALAYE

Nigba ti Jesu n pa owe iyanu wọnyii, O sọ nipa "ohun ijinlẹ ijọba ọrun" (Matteu 13:11). Lẹsẹẹsẹ O bẹrẹ si i maa sọ itumọ diẹ ninu awọn "ohun ijinlẹ" yii ninu awọn owe ti o n pa. Ninu owe ti Afunrugbin, a ri i pe a ni lati gba "awọn ọ̀rọ' Rẹ̀ gẹgẹ bi a ti n fún irugbin naa, nitori "ọ̀rọ wọnni ti mo sọ fun nyin, ẹmi ni, ìye si ni" (Johannu 6:63). Bayii ni a si n gbin Ijọba naa sinu ọkàn ẹni kọọkan. Ninu owe ti Alikama ati Èpo, O kọ́ ni pe gẹgẹ bi Ọrọ Iye Rẹ̀ ti n dagba ninu ọkàn, bakan naa ni a n gbin "awọn ọmọ ijọba" ninu ayé.

Ninu awọn owe ti a sọ nipa wọn ṣaaju, Jesu n sọ nipa awọn eniyan kọọkan ti i ṣe ọmọ ibilẹ ninu Ijọba iyanu yii. Ṣugbọn ninu awọn owe meji ti o wà niwaju wa nisisiyii, Jesu n sọ nipa Ijọba yii ni apapọ. Nitori Ijọba Ọrun tayọ ohun ijinlẹ ninu ọkàn. Awọn ibẹrẹ wọnyii le dabi ohun kekere ati eyi ti kò ni laari loju ẹlomiran, bẹẹ ni wọn si ri nigba ti a ba fi wọn wé ohun ti n bọ̀ wá ṣẹlẹ; nitori Jesu kọ́ ni pe "ibẹrẹ kekere wọnyi" yoo maa dagba siwaju ati siwaju, gẹgẹ bi irugbin mustardi kekere, ni ọjọ kan Ijọba yii yoo si kún gbogbo aye (Daniẹli 2:35-44).

### Wóro Irugbin Mustardi

Irugbin mustardi ri ribiti o si kere pupọ, awọn eniyan igba laelae si maa n fi pa owe pe on ni o kere ju lọ ninu gbogbo irugbin. Nigba kan ti Jesu n bá awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ sọrọ O ni, "Bi ẹnyin ba ni igbagbọ́ bi wóro irúgbin mustardi, ẹnyin o wi fun òke yi pe, Ṣi nihin lọ si ọ̀hun, yio si ṣi: kò si si nkan ti ẹ ki yio le ṣe" (Matteu 17:20). Oun ko wi pe "Bi woro iyanrin kan" nitori iyanrin kò ni ìyè ninu; ṣugbọn woro irugbin mustardi, bi o ti kere tó ni, o ni ohun ijinlẹ iyanu ti ìyè ninu, o si le dagba. Igbagbọ́ gbogbo awọn Onigbagbọ tootọ si jẹ igbagbọ́ ààyè, a si maa dagba bi wọn ti n gbọ́ Ọrọ naa (Romu 10:17).

Nitori naa o ṣe deedee gan an nigba ti Jesu yan irugbin kekere yii lati fi ṣe apẹẹrẹ ibẹrẹ Ijọba naa, nitori Ijọba Ọrun jẹ eyi ti o kun fun ìye lọpọlọpọ; Ọba rẹ̀ ni "ajinde ati iye," O si le dagba. "Ọkunrin" kan mu irugbin yii o si gbin in sinu "oko" rẹ̀. Niwọn igba ti o jẹ pe Ọmọ eniyan ni Afunrugbin ninu awọn owe mejeeji ti o ṣiwaju, a le sọ pe Oun naa ni Afunrugbin ninu owe yii, "oko" Rẹ̀ si ni ayé yii. Iṣẹ Jesu lati fi idi Ijọba Ọrun kalẹ bẹrẹ ni ayé yii.

Ni ibẹrẹ Akoko ti Ihinrere, Johannu Baptisti, ẹni ti i ṣe òléwá fun Ọba naa, farahàn: ohun ti o si bẹrẹ si i kede fun awọn eniyan ni, "Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀." Lẹyin oṣu mẹfa Jesu bẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀, O si bẹrẹ si i kede ironupiwada bakan naa fun awọn eniyan; ni gbogbo akoko iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀ ni O si waasu "Ihinrere ti ijọba yi." Ijọba Ọrun ti O wa fi idi rẹ kalẹ jẹ koko kan pataki ninu ẹkọ Rẹ̀ gbogbo. On ni koko pataki ju lọ ninu adura nla nì ti O kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, "Ki ijọba rẹ de; Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹ̃ni li aiye." Nipasẹ iṣẹ-iranṣẹ kukuru ti O ṣe ni a gbin "wóro irugbin mustardi" yii. A ti fi ibẹrẹ Ijọba naa lelẹ O si ti dagba; nitori a paṣẹ a si fi agbara fun awọn Apọsteli ati awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati kede Ihinrere ti Ijọba kan naa. Igbesẹ yii ninu itẹsiwaju Ijọba Ọrun, eyi ti awọn eniyan le ṣe alaifi oju rí, le dabi ẹni pe o kere, ṣugbọn Jesu ni awọn nnkan miiran lati sọ fun wa nipa Ijọba yii.

### Eyi ti o Tobi Ju Lọ ninu Gbogbo Ewebẹ

Awọn arinrin-ajo ti wọn ti bẹ Ilẹ Mimọ nì wo sọ fun wa pe iru irugbin mustardi yii, eyi ti Jesu n tọka si, ṣi n gbilẹ daradara ni Palẹstini ti wọn n ga to bẹẹ ti irisi wọn jọ ti igi gan an ju ti ewebẹ lọ. Ewebẹ ọtọ yii, ti o bẹrẹ lati irugbin kekere ti o si dagba bi igi, ni apẹẹrẹ ti Jesu yàn lati fi ṣe akawe titobi ikẹyin ti Ijọba Ọrun. Bi awọn wolii

Majẹmu laelae ti n ṣe iwadi ohun ijinlẹ awọn ileri igba laelae wọnni, wọn ri iran Ijọba ologo yii; nipa imisi ayọ ohun ti Ẹmi Ọlọrun ṣipaya fun wọn yii, wọn sọ asọtẹlẹ titobi rẹ, wọn si kọrin ibukun rẹ pẹlu.

Nigba ti wolii Esekiẹli n kọ akọsilẹ nipa Ijọba yii, a fun un ni apẹẹrẹ ti o dabi owe ti a n kọ́ ẹkọ nipa rẹ yii: "Bayi ni Oluwa ỌLỌRUN wi; emi o mu ninu ẹka ti o ga jùlọ, ninu igi Kedari giga; emi o si lọ́ ọ, emi o ke ọ̀munú ẹka kan kuro ninu ọ̀munú ẹka rẹ̀; emi o si gbìn i sori oke giga kan ti o si hàn: lori oke giga ti Israẹli ni emi o gbìn i si, yio si yọ ẹka; yio si so eso, yio si jẹ igi Kedari daradara; labẹ rẹ̀ ni gbogbo ẹiyẹ oniruru iyẹ́ o si gbe; ninu ojiji ẹka rẹ̀ ni nwọn o gbe" (Esekiẹli 17:22, 23).

Isaiah fi Ijọba naa wé oke giga kan, ti o ga ju gbogbo òke iyoku lọ: "Yio si ṣe ni ọjọ ikẹhin, a o fi òke ile OLUWA kalẹ lori awọn òke nla, a o si gbe e ga ju awọn òke kékèké lọ; gbogbo orilẹ-ède ni yio si wọ́ si inu rẹ̀. Ọ̀pọlọpọ enia ni yio si lọ, nwọn o si wipe, "Ẹ wá, ẹ jẹ ki a lọ si òke OLUWA, si ile Ọlọrun Jakọbu; On o si kọ́ wa li ọ̀na rẹ̀, awa o si ma rìn ni ipa rẹ̀; nitori lati Sioni ni ofin yio ti jade lọ, ati ọ̀rọ OLUWA lati Jerusalẹmu. On o si dajọ lãrin awọn orilẹ-ède, yio si ba ọ̀pọlọpọ enia wi: nwọn o si fi idà wọn rọ ọbẹ-plau, nwọn o si fi ọ̀kọ wọn rọ dojé; orilẹ-ède ki yio gbe idà soke si orilẹ-ède; bẽni nwọn ki yio kọ́ ogun jijà mọ" (Isaiah 2:2-4).

Nigba ti Daniẹli n sọ itumọ ala Nebukadnessari, o fi Ijọba naa we okuta: "Nigbana li a o si fọ irin, amọ̀, idẹ, fadaka ati wura pọ̀ tũtu, o si dabi iyangbo ipaka nigba ẹ̀run; afẹfẹ si gbá wọn lọ, ti a kò si ri ibi kan fun wọn mọ́: okuta ti o si fọ ere na si di òke nla, o si kún gbogbo aiye … Li ọjọ awọn ọba wọnyi li Ọlọrun ọrun yio gbe ijọba kan kalẹ, eyi ti a kì yio le parun titi lai: a kì yio si fi ijọba na le orilẹ-ède miran lọwọ, yio si fọ tutu, yio si pa gbogbo ijọba wọnyi run, ṣugbọn on o duro titi lailai" (Daniẹli 2:35, 44).

Sekariah sọ fun wa nipa Ọba ti yio gbé Ijọba yii kalẹ ti yoo si ṣakoso rẹ̀; "OLUWA yio si jọba lori gbogbo aiye: li ọjọ na ni OLUWA kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si jẹ ọkan" (Sekariah 14:9). Bẹẹ ni Isaiah si ṣe apejuwe iwa rere Ọba yii lọna ti o wú ni lori, eto Ijọba Rẹ̀ ati bi yoo ṣe maa pọ̀ si i: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yoo si wà li ejika rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ Alade Alafia. Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹkun: lori itẹ Dafidi, ati lori ijọba rẹ̀, lati ma tọ́ ọ ati lati fi idi rẹ̀ mulẹ, nipa idajọ, ati ododo lati isisiyi lọ, ani titi lai. Itara OLUWA awọn ọmọ-ogun yio ṣe eyi" (Isaiah 9:6, 7).

JESU ni Ọba naa. Lai pẹ yoo fi itẹ Rẹ̀ nibi ti O ti n ṣe Alagbawi silẹ, yoo si tun pada wá si ayé lati gbe Ijọba Rẹ̀ kalẹ fun ẹgbẹrun-ọdun. Nigba naa ni a o mu awọn asọtẹlẹ igba nì gbogbo ṣẹ. Nigba naa ni a o dahun adura laelae nì, "Ki ijọba rẹ de. Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe li aiye, bi ti ọrun." Paulu ni, "Nitori awa mọ̀ pe gbogbo ẹda li o jumọ nkerora ti o si nrọbi pọ̀ titi di isisiyi. Kì si iṣe awọn nikan, ṣugbọn awa tikarawa pẹlu, ti o ni akọso Ẹmi, ani awa tikarawa nkerora ninu ara wa, awa nduro dè isọdọmọ, ani idande ara wa" (Romu 8:22, 23).

Egún ti ẹ̀ṣẹ mu wá sori ayé ti di ẹrù nla ti o n wọ gbogbo eniyan lọrun, ko si si iru ijọba-kijọba ti eniyan ti i gbe kalẹ tabi ti wọn le gbe kalẹ, ti o le gbe ẹru ègún naa kuro. Afi igba ti Jesu ba joko lori itẹ Dafidi ti O si n ṣakoso ninu ododo, ni a o tó mu ègún yii kuro. Nigba naa ni ilẹ aṣálẹ̀ yoo tanna bi itanna. Nigba ti "igi mustardi" ba dagba tán, nigba naa ni awọn ẹyẹ oju ọrun yoo ri aabo labẹ ẹka rẹ̀, nitori nigba naa ni a o mu ileri ti a ṣe fun Abrahamu ṣẹ: "Ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye."

**Ijọba na n bọ**

**Ẹ sọ itan na,**

**A oo gbe asia Ọlọrun soke!**

**Aye yoo kun fun**

**Imọ ati ogo Rẹ̀**

**Gẹgẹ bi omi ti bo okun!**

### Iwukara ati Iyẹfun

Akoko ti Jesu fara hàn laaarin awọn Ju, jẹ akoko ti wọn n wo ọna fun Ijọba kan ti n bọ̀ nitori a ti sọ pupọ nipa titobi ati ogo rẹ̀ daradara, a si ti ṣeleri igbekalẹ rẹ ni asọtunsọ ninu Majẹmu Laelae, gẹgẹ bi a ti ri i ninu awọn ẹsẹ Iwe Mimọ́ ti a kọ silẹ ṣaaju. Ṣugbọn ogunlọgọ awọn eniyan wọnyii ati paapaa ọpọlọpọ awọn ọmọ-ẹyin Jesu ni wọn n wo ọna fun Ijọba kan ninu ayé yii ti o logo ti o si lagbara. Òye wọn kuru pupọ nipa Ijọba ti ẹmi ti Jesu n waasu. Ohun ijinlẹ ni eyi jẹ. "Nigbati awọn Farisi bi i pe, nigbawo ni ijọba Ọlọrun yio de, o da wọn li ohùn pe, Ijọba Ọlorun ki iwá pẹlu àmi; bẽni nwọn ki yio wipe, Kiyesi i nihin! tabi kiyesi i lọhun! sawõ, ijọba Ọlọrun mbẹ ninu nyin" (Luku 17:20, 21).

O hàn gbangba lati inu ọrọ yii pe Jesu n sọrọ nipa ibẹrẹ Ijọba Rẹ̀ -- Akoko Ihinrere, nigba ti a n gbe Ijọba naa kalẹ ninu ọkàn, gẹgẹ bi ẹkọ ti a ti kọ́ ṣiwaju, ayé ko si ti i le fi oju ri i. Ipo yii ni a gbagbọ pe a n fi iwukara ti a fi sinu iyẹfun ṣe apẹẹrẹ rẹ̀. "Iwukara" yii gẹgẹ bi o ti lagbara to nipa iṣẹ rẹ ninu oṣuwọn iyẹfun mẹta nì, dabi agbara Ihinrere, **ki i ṣe** lori ayé, ṣugbọn ti o n ṣiṣẹ lọ ni ọna ijinlẹ ati iyanu **ninu** aye ni Akoko Oore-ọfẹ yii. Obinrin naa fi iwukara rẹ̀ "pamọ" sinu iyẹfun nì. Bẹẹ gẹgẹ ni "awọn ohun ijinlẹ ti Ijọba na" pamọ kuro lọdọ awọn eniyan ti wọn

kọ Kristi silẹ ninu ayé yii.  Ṣugbọn sibẹ "a o si wasu Ihinrere Ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède" titi "gbogbo rẹ̀" yoo fi di wiwu, "nigbana li opin yio si de."

Ọlọrun ninu ọgbọn awamaridi Rẹ̀ ti pinnu, O si ti yan ayé yii, nibi ti ẹ̀ṣẹ pọ rekọja, gẹgẹ bi "oko" Rẹ̀ lati ṣe aṣeyori imuṣẹ Ijọba Rẹ̀ ti o logo, eyi ti awọn wolii ti sọ asọtẹlẹ rẹ̀. Nihin naa ni O si ti n yan ti O si n sọ awọn ọmọ Ijọba yii di pipe. Nihin ni a ti "njà ija rere ti igbagbọ́."  Bi o ti wu ki "ija" naa ti dabi ija asan to loju awọn miiran, sibẹ Oluwa wa Jesu Kristi mu "Ihinrere ti Ijọba yi" wá si aye, Oun ati awọn Apọsteli Rẹ̀ si waasu rẹ, nipasẹ rẹ ni o si ti ṣi ilẹkun Oore-ọfẹ fun ẹya gbogbo, orilẹ-ède gbogbo, ati ède gbogbo.  Ihinrere yii kò ti i sọ agbára rẹ̀ nù rí. "Oluwa na si wi fun ọmọ-ọdọ na pe, Jade lọ si opópo, ati si ọ̀na ọgbà, ki o rọ̀ wọn lati wọle wá, **ki ile mi le kún"** (Luku 14:23).

**"Iṣẹ ti a ba fi ọpọ ọgọrun ọdun ṣe**
**Ni a gbọdọ pari bi oorùn ti n wọ,**
**Ni gbogbo ilẹ ni a gbọdọ kede**
**Orukọ ti n gbala, pẹlu itara kikun."**

## AWỌN   IBEERE

1. Lọna wo ni "wóro irugbin mustardi" fi dabi Ijọba Ọrun?
2. Ta ni "ẹniti" o gbin irugbin yii duro fun?
3. Ni ọna wo ni idagbasoke irugbin mustardi fi dabi Ijọba Ọrun?
4. Ki ni awọn "ẹyẹ" ti wọn ri ibugbe ninu ẹka ewebẹ nla yii duro fun? Ninu awọn ileri ti a ṣe fun Abrahamu ewo ni owe yii n ṣe apẹẹrẹ rẹ̀?
5. Nibo ati lọna wo ni ifilelẹ Ijọba yii ṣe n bẹrẹ?
6. Ki ni "òke nla" ti o wà ninu Isaiah 2:2-4 n ṣe apẹẹrẹ rẹ̀?
7. Darukọ awọn wolii Majẹmu Laelae ti wọn sọ asọtẹlẹ nipa Ijọba yii.
8. Ki ni yoo jẹ iṣẹgun nla ti Ijọba yii nikẹyin?
9. Lọna wo ni iṣẹ "iwukara" ninu iyẹfun fi dabi ohun ti o n ṣẹlẹ ninu fifi idi Ijọba yii kalẹ?